# ***Òwónrín Méjì***

***Él está comerciando y se queja de no hacer ganancias. Debe ofrecer sacrificio y sus caminos estarán abiertos. Él eclipsará a sus enemigos.***

*Síbà lé mi*
*Kí n síbà lé ọ*
*Bí Yèrèpé ti síbà lÉèşún*
*Ká jọ síbà léraa wa*
*A dífá fún Sièjidé*
*Sièjidé ti ó móọ sòwò Ọjà ń níná*
*Ọmọ Ọba ni Sièjidé lóde Òyó*
*Ọjà ní móọ ná*
*Ó wáá tajà tajà*
*Ọjàa rè ò tà*
*Ó bá mú eéji kún ẹéta*
*Ló bá tọ Òrúnmìlà lọ*
*Ó ké si àwọn "Òwón Owó làá náwó mini"*
*Àwọn "Òwón omi làá pèsun"*
*Àwọn "N tó bá wón làá pè níyàn"*
*Ó ní kí àwọn métèèta ó yẹ òun lóókan ibò wò*
*Wón níwọ Sièjidé*
*"Ó sòwò sòwò ọjàà rẹ ò tà lo dá Ifá yìí sí"*
*Ẹbọ ní kó rú*
*Ọjàà ré ó sí móọ tà*
*Sièjidé bá rúbọ*
*Ó rúbọ tán ó bá bèrè síí lá*
*N ní wá ń jó n ní ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Síbà lé mi*
*Kí n síbà lé ọ*

*Bí Yèrèpé ti síbà lÉèşún*
*Ká jọ síbà léraa wa*
*A dífá fún Sièjidé*
*Sièjidé ti ó móọ sòwò Ọjà ń níná*
*Èyí tíí sọmọ ọba lóde Òyó*
*Ệbọ ń wón ní ó şe*
*Ệ yáa wá rajà ọmọ ọba*
*Ệ pò sinsin wáá ẹ wáá rajà ohùn yìí ó wón!*
*Ệ yáa wá rajà ọmọ ọba.*

***Apóyese en mí.***
***Para que yo me pueda apoyarme en ti.***
***Así como las ortigas se apoyan en las salvajes hiervas.***
***Nosotros nos apoyamos unos a los otros.***
***Lanzaron adivinación para Sièjidé, que tomaría el comercio como su medio de sustentación.***
***Sièjidé era la hija del rey de Òyó.***
***Ella se había especializado en marketing, y aunque negociaba y negociaba, no obtenía buenos dividendos.***
***Ella adicionó dos cowríes a tres y vino a ver a Òrúnmìlà.***
***Ella llamó a los sacerdotes:***
***“Òwón Owó làá náwó mini”***
***“Òwón omi làá pèsun”***
***“N tó bá wón làá pè níyàn”***
***Quienes lanzaron Ifá usando ibò para ella.***
***Le dijeron que debía ofrendar para obtener buenas ganancias.***
***Ella sacrificó y empezó a ver buenas ganancias en su comercio.***
***Entonces ella se regocijó y alabó a sus babaláwos.***
***Ellos se regocijaron y alabaron a Ifá.***
***Apóyese en mí.***
***Para que yo me pueda apoyarme en ti.***
***Así como las ortigas se apoyan en las salvajes hiervas.***
***Nosotros nos apoyamos unos a los otros.***
***Lanzaron adivinación para Sièjidé, que tomaría el comercio como su medio de sustentación.***
***Y aquella que era también princesa del reino de Òyó, sacrificó en la forma en que ellos habían prescrito.***

***Por consiguiente venga y compre de los artículos del niño del rey.***
***Usted junte a toda la muchedumbre para comprar los escasos artículos.***
***Venga y compre de los artículos del niño del rey.***

*Akarasangba Òşùmàrè*
*Òşùmàrè náà Akarasangba*
*A dífá fún Ìrókò Ògò*
*Níjó ti ń bẹ láàrin Òtá sáńgílítí*
*Ààrin Òtá ti òún wà yí?*
*Òun le şégun báyìí*
*Wón ni kó rúbọ*
*Ó bá rúbọ*
*Ló bá ga ju gbogbo pàňti igbó*
*Ló bá tẹ gbogbo àwọn òtá è mólè*
*N ní wá ń jó n ní ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Akarasangba Òşùmàrè*
*Òşùmàrè náà Akarasangba*
*A dífá fún Ìrókò Ògò*
*Níjó ti ń bẹ láàrin Òtá sáńgílítí*
*Ẹ̀bọ n wón ni ó şe*
*Ó wáá gbébọ ńbè*
*Ó rúbọ*
*Ìrókò Ògò nikàn ló yọrí jú wón lọ*
*Ìrókò Ògò.*

***Akarasangba Òşùmàrè***
***Òşùmàrè náà Akarasangba***
***Lanzó adivinación para Ìrókò Ògò, cuando se encontraba rodeado de enemigos potenciales.***

***¿Podré vencer a estos enemigos que están dónde yo moro? Él se preguntó. Ellos le dijeron que debía sacrificar. Así lo hizo.***
***Él creció por encima de todos los céspedes y arbustos del bosque.***
***Y controló a todos sus enemigos totalmente.***
***El bailó y alabó a sus babaláwos.***
***Ellos alabaron a Ifá.***
***Akarasangba Òşùmàrè***
***Òşùmàrè náà Akarasangba***
***Lanzó adivinación para Ìrókò Ògò, cuando se encontraba rodeado de enemigos potenciales.***
***El sacrificio fue la solución prescrita para él; cosa que escuchó y realizó.***
***Ìrókò Ògò, los ha eclipsado a todos.***
***Ìrókò Ògò.***

# Òwónrín Ogbè

***Se deberá seguir la senda ancestral para ser feliz. Todo lo que se haga se deberá rendir respeto a la línea ancestral, y guardarse de tener un buen carácter. Ifá lo manda no vengar desaires hechos a él.***
***Si cualquiera le pide prestado algo a él y el peticionario no podría encontrar lo original para devolver, y está listo a reemplazar el artículo pedido con una réplica; esto él debe coleccionarlo porque si él se niega y está decidido a cobrar, él o ella lo sentirán muchísimo.***

*Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*Awo Jéésù ló dífá fún Jéésù*
*Níjó ti ń tòrun bò wálé ayé*
*Ilé ayé tóun ń lọ yìí*
*Òun ó şe le rí èèyàn kó jọ?*
*Ó bá tójú aàrùún iténí*
*Ogóji àdibò*

*Wọ́n ní kó tọ̀ Ifá lọ̀*
*Ńgbà ó dódò Ifá*
*Wọ́n gbé Ifá kalẹ̀*
*Erín ńlá yọ̀ kàngí lójú ọ̀pọ́n*
*Nígbà ti wọ́n ó rìí*
*Wọ́n rí Ọ̀wọ́nrín lọ́wọ́ ọ̀tún*
*Ogbè lọ́wọ́ òsi*
*Wọ́n ní ó pè pèè pè*
*O ò rí nàà lo bèèrè sí?*
*Wọ́n ní ó lọ̀ó fi ilá rúbọ̀*
*Wọ́n rúbọ̀ tán*
*Ó tún pè pèè pè*
*Kò tún rí*
*Wọ́n ní kó tún kó ọ̀rúnlá wá*
*Àti ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ owó*
*Ó tún kó o wá*
*Wọ́n ní kó ṣe ọ̀bè ilá lọ́tọ̀*
*Kó si se ọ̀rúnlá*
*Kó gún Iyán*
*Kó si ro ọ̀kà*
*Kó wáá loodi ilú*
*Kó lànà gbọ̀ọ̀rọ̀ já orítа*
*Kó wáá kọ́lé ganta níbẹ̀*
*Kó wèwù gbọ̀ọ̀rọ̀*
*Kó si di Àmùrè pupa*
*Kó mọ́ọ̀ wáá jó*
*Kó si mọ́ọ̀ pe babaa rè*
*Gbogbo ohun tóo ni ò tó*
*Gbogbo è ní ó sùn ó bò*
*Jésù bá ṣe béè*
*Ó loodi ilú*
*Ó kọ́lé ganta sórítа*
*Ó kó àwọn ọ̀mọ̀ kéékèèké jọ̀*

Ní bá ń kọrin
Ní ń lọ ní ń bò
Yóó bàá jó lọ, yóó tùún jó bò
A si tún kó sínú ilé òhún
Àwọn èèyàn bá pé pitimu
N ní wá ń jó n ní ń yò
Ní ń yin àwọn Babaláwo
Àwọn Babaláwo ń yin Ifá
Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí
Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè
Awo Jéésù ló dífá fún Jéésù
Níjó ti ń tòrun bò wálé ayé
Wón ní ó rúbọ kó lè bà léni
Kó lè bà léni léyin piti piti piti
Òrúnmìlà ní ó rúlá
Ó rúlá béè ni ò rénikan
Ó ni ó şe ijẹ şe imu
Kó loodi ilú
Kó lòó kólé ganta síbè
Ní wáá ń jóó lọ níbè
Ni ń yò níbè
Ní wá ń dárin
Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè
Bàbà fọrúnlá jẹkà ó yo
Pèkútú yẹkè
Wòó, wòó, wòó, wòó
Ni ń paté
Ńgbà ó yá
Àwọn èèyàn bá ri pé oriin rè dùn
Wón bá ń bá a kọ ó
Ní bá tún ń şe
Òwónrínşogbè, Òwónrínşogbè
Bàbà fọrúnlá jẹkà ó yo

*Òwónrínşogbè*
*Wòó, wòó, wòó, abbi*
*Ńgbà ó papé di ọwó iròlé*
*Ti ó móọ bò wálé*
*Àwọn méjì tèlé e*
*Ó kó méjì òhún*
*Ó lòó fi han Ifá*
*Ifá pé kó loodi ilú kejí*
*Kó tún lòó şe bákan náà*
*Kó kólé ganta síbè*
*Kó lànà gbọọrọ síbè*
*Kó tún móọ jó*
*Ó tún şe béè*
*Ó tún dárin*
*Ní ń şe Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*Bàbà fọrúnlá jẹkà ó yo*
*Pèkútú yẹkè*
*Wòó, wòó, wòó, abbi*
*Gbogbo èèyàn tún bá a ńbè*
*Wón bá tún ń jó*
*Ńgbà ó di ọwó àsálé*
*Àwọn méjì tún tèlé e*
*Ó tún loodi ilú kẹta*
*Ó tún dárin*
*Ó tún jó*
*Ó tún rí méjì miin*
*Ńgbà ó tún yá*
*Ó loodi ilú kẹrin*
*Ó tún jó jóó jó*
*Ó tún dárin*
*Ní ń pé Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*Bàbà fọrúnlá jẹkà ó yo*
*Pèkútú yẹkè*

*Ọ̀wónrínşogbè, Ọ̀wónrínşogbè*
*Bàbà fọrúnlá jẹkà ó yo*
*Ọ̀wónrínşogbè*
*Wòó, wòó, wòó, abbi*
*Ó bá tún bèèrè sìí jó*
*Ǹgbà tí ó mée relé*
*Tí ilé tún şú dèdèèdè*
*Àwọn méjì tún tèlé e*
*Ó bá kó àwọn méjèèjọ*
*Ó kó wọn lòó han Ifá*
*Ifá pé iwọ Jéésù*
*Nǹkaan ré ó móọ jọ*
*Ifá pé púpò ló pè*
*Şùgbón diè ló ri*
*Ó ni şùgbón diè tóo ri un*
*Yóó di ǹlá mó ọ lówó*
*Ifá ni móọ lọ iwọ Jéésù*
*Jéésù bá lọ*
*Béè ni Jéésù şe tóbi láyé tée dòní*
*Ifá pé eléyiun ó tóbi láyé.*

***Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè***
***El sacerdote de Jesús, lanzó adivinación para Jesús, cuando venía del Cielo a la Tierra.***
***¿Cómo seré capaz de obtener seguidores en la Tierra? Él preguntó.***
***Él encontró cinco peniques por la estera extender.***
***Y cuarenta peniques por el ìbò lanzar.***
***Y se fue a consultar a Ifá. Allí le dijeron que había salido el gran Odù de Ọ̀wónrínşogbè.***
***Ellos le dijeron que él trataba de llamar a una asamblea sin ninguna razón de consultar Ifá. Le pidieron que sacrificara okra (Quimbombo).***

*Él sacrificó y llamó y llamó, pero nadie venía.*
*Y le fue pedido traer quimbombo seco de la tierra, y un poco de dinero. Le dijeron que preparase una sopa de quimbombo fresco y otra sopa de quimbombo seco, además debía machacar ñame y hacer pudin de harina de ñame.*
*Él debía proceder entonces a las afueras de la ciudad.*
*Él debía hacer un camino recto a la unión del camino.*
*Él debía construir una choza allí en la unión.*
*Y atarse un cinturón rojo en su cintura.*
*Allí debía bailar y cantar, invocando el espíritu de su padre.*
*"Una vez, invoques a tu padre, todo lo que desees, llegará en gran abundancia". Jesús hizo todo como se le indicó.*
*Y allí delante de la choza, se congregó una gran multitud para observarle, cantar y danzar, en sus invocaciones.*
*El bailó y alabó a sus babaláwos.*
*Ellos alabaron a Ifá.*
*Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*El sacerdote de Jesús, lanzó adivinación para Jesús, cuando venía del Cielo a la Tierra.*
*Ellos le pidieron sacrificar para tener seguidores.*
*Ofreció quimbombo, pero sin brindar aún el ñame.*
*Le pidieron entonces brindar alimentos y bebidas.*
*Y así lo hizo, reuniéndose una gran multitud a su alrededor.*
*Y él continuó cantando e invocando.*
*Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*El Padre usó sopa de quimbombo y pudín de harina de ñame para comer con satisfacción de todos.*
*Pèkútú yẹkè*
*Wòó, wòó, wòó, wòó*
*Después de un corto tiempo, él estuvo aplaudiendo mucho.*
*El pueblo supo que sus canciones eran muy melodiosas y se unieron a él en sus cantos e invocaciones.*
*Y él gritó estentoreamente:*
*¡Òwónrínşogbè; Òwónrínşogbè!*
*El Padre usó sopa de quimbombo y pudín de harina de ñame para comer con satisfacción de todos.*
*¡Òwónrínşogbè!*
*Wòó, wòó, wòó, wòó*

*Él aplaudió y aplaudió hasta que oscureció y antes de retirarse a dormir.*
*Dos hombres le siguieron y él los tomó y los mostró a Ifá.*
*Ifá le pidió que los llevase al lado Oeste de la ciudad y allí desarrollase lo mismo que había hecho.*
*Y así él lo volvió a realizar.*
*Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*El Padre usó sopa de quimbombo y pudín de harina de ñame para comer con satisfacción de todos.*
*Pèkútú yẹkè*
*Wòó, wòó, wòó, wòó, el aplauso sonó*
*El pueblo le volvió a ver y se unieron a él en sus cantos y rezos hasta bien entrada la noche.*
*Dos personas más se le unieron como seguidores.*
*Y se fueron a la parte Norte de la ciudad y allí conformaron la misma ceremonia de cantos y rezos.*
*Luego se fueron a la parte Sur de la ciudad y allí repitieron sus acciones.*
*Y cantaron y rezaron diciendo Pèkútú yẹkè pèkútú yẹkè*
*El Padre usó sopa de quimbombo y pudín de harina de ñame para comer con satisfacción de todos.*
*Pèkútú yẹkè*
*¡Òwónrínşogbè; Òwónrínşogbè!*
*El Padre usó sopa de quimbombo y pudín de harina de ñame para comer con satisfacción de todos.*
*¡Òwónrínşogbè!*
*Wòó, wòó, wòó, wòó*
*Y antes de terminar sus cantos y rezos, se le unieron hasta llegar a ocho, a quienes mostró a Ifá.*
*Ifá dijo: -¡Jesús, tú esfuerzo será premiado!-*
*-¡Tus cosas serán como las desees para ellos!-*
*-¡Llamaste a muchos y vinieron a unírsete unos pocos!-*
*-¡Pero ellos llegarán a convertirse en grandes hombres!-*
*Ifá dijo:-¡Entonces ve y haz lo tuyo Jesús!-*
*Y así fue como Jesús y sus seguidores fueron grandes.*
*Ifá dice que esta persona, será muy bien famosa y reconocida por todos.*

*Ó şe mí*
*Mo şé san*
*Adié dà mí lóògùn nù*
*Mo fó ợ léyìn*
*Igbá oró ì í fó*
*Òşùnwòn Oró ò ya bòrò bòrò*
*Igbá táa bá fi wín Ợkà*
*Làá fií san án*
*A dífá fún Òwónrín*
*Ti ń lợ rèé so Ìlèkè mó ợmợ Ogbè lórùn*
*Nígbà ìwásè*
*Ợsàn Àgbálùmò ni Òwónrín gbin*
*Ó si tợrợ kòkò ògi tó jádií lówó Ogbè*
*Ó fi bợ ợrùn àgbálùmò òhún ńtorí ewúré*
*Ợsàn bá dàgbà ó ti bẹrẹ síí so*
*Líló wáá kan kòkò ògi ti Ogbè fún Òwónrín*
*Ó bá ní kí Òwónrín ó fún òun ni kòkò òun*
*Òwónrín ni bóó láá wa ti şe?*
*Ìkòkò rẹ lòún fi bợ ợsàn lórùn yìí*
*Ợsàn náà ní si ti ń so yìí*
*Ogbè ní dandan ikòkò tòun lòún ó lò*
*Òun ò féé lo kòkò ẹlòmiin*
*Béè ni ón şe mú ợsàn*
*Wón bá gé àgbálùmò tó so látòkè délè*
*Léyin ợjó díè*
*Ợmợ Ogbè tó ilé ợkợó lợ*
*Wón si gbọdò so Ìlèkè mó ợmợ lórùn*
*Kó tóó lợ ilé ợkợ*
*Orísiírísií Ìlèkè ni si ń bẹ lódò Òwónrín*
*Ogbè bá sáré lòó yá òkan lódò òré è*
*Òwónrín fún Ợmợ Ogbè ní Ìlèkè*
*Ó wợ ilé ợkợ tòun tilèkè lórùn*

*Ọjó kẹtàdínlógún ni àwọn ọmọ Obìnrin sìí lọ ilée bábá wọn*
*Ti wón ó jàá Ìlèkè lórùun wọn*
*Òwónrín bá takú pé wón ò gbọdò já Ìlèkè òun*
*Kín ló dé?*
*Òwónrín kò jálè*
*Ó ní wọn ò gbọdò já Ìlèkè*
*Wón bó Ìlèkè sókè*
*Kò bó*
*Wón sí gbọdò já Ìlèkè lójó náà*
*Bóo làwọn ó ti wáá ṣe?*
*Òwónrín ni èyín ti gbàgbé ní*
*Igbá oró kan a móọ fó ni?*
*Oṣùnwòn oró kan ì í fàya bòròbòrò*
*Igbá táa bá fi wínkà*
*Làá fíí san án*
*Bádié bá da ni lóógùn nù*
*Ẹ̀yin è làá fó*
*Ẹ̀ni ó bá ṣe ni*
*À á ṣéé san ni*
*Ṣebí òún gé ọsàn òun ní lójó kiiní*
*Hain, kí wón ó gé iyuun náà!*
*Béè ni ón ṣe gé ọmọ lórí*
*Ní ón bá yọ Ìlèkè fún Òwónrín.*
*Ogbè ni hàáà*
*Àṣé oró àkókó*
*Àṣé kò dàbí oró àdágbèyin?*
*Ifá yìí kó ni ní sùúrù*
*Àti fifí làákàyè gbé ilé ayé*
*Àyin éyin ni Ogbè ń yin àwọn Babaláwo*
*Ó ṣe mí*
*Mo ṣé san*
*Adié dà mí lóògùn nù*

*Mo fó ợ léyìn*
*Igbá oró ì í fó*
*Òşùnwòn Oró ò ya bòrò bòrò*
*Igbá táa bá fi wín Ợkà*
*Làá fìí san án*
*E dákun iwà rere ni ẹ jé a móợ hù ẹ dáákun!*
*Òwónrín so Ìlèkè mó ợmợ Ogbè lórùn*
*Kó bá já sórí ikú.*

***Él me despreció.***
***Yo me vengué.***
***Una gallina desparramó mi medicina.***
***Yo rompí sus huevos.***
***La jícara de carga no se romperá.***
***Las jícaras de carga no se rasgan, ni se salen fácilmente.***
***La jícara usada para pedir prestado el maíz es la que debe usarse para reembolsarlo.***
***Lanzaron Ifá para Òwónrín, cuando venía a atar cuentas en el cuello de la hija de Ogbè.***
***En días atrás, Òwónrín había plantado un árbol de cereza y pidió prestada una olla de almidón sin fondo de Ogbè.***
***Él la usó para proteger el árbol de cereza creciente de las cabras en su alboroto.***
***La planta de cereza dentro de un periodo corto de tiempo creció y germinó extensivamente.***
***Ogbè estaba sin embargo, necesitó de la olla de almidón prestada a Òwónrín.***
***Él se la pidió a Òwónrín, quien asombrado le dijo que su olla era la que había puesto en el árbol de la cereza.***
***El árbol ha empezado a germinar, él explicó.***
***Ogbè se negó a diciendo que quería su propia olla particular, y no quiso una nueva.***
***Quitarla, era cómo si el árbol fuera tumbado, ya que era grande la magnitud de germinación para quitar la olla de almidón.***
***Después de algún tiempo, la hija de Ogbè estaba bastante madura para casarse. Y es un imperativo que deben atarse las cuentas en su cuello, antes de que ella se casara.***

*Sin embargo, Òwónrín era el custodio mayor de todos los tipos de cuentas.*
*Ogbè corrió rápidamente para pedir prestada una de su amigo.*
*Òwónrín le dio la cuenta que él deseó a Ogbè.*
*Ella lo ató en su cuello y se casó.*
*En el decimoséptimo día, la novia tiene que regresar a la casa de su padre sin embargo, con tal que las cuentas se cortarían y se tirarían fuera de ella.*
*Òwónrín se negó entonces descaradamente a permitirles cortar sus cuentas del cuello de la señora.*
*¿Por qué? Ellos preguntaron.*
*Òwónrín era la inclinación del infierno.*
*Él se negó a permitirles cortaran fuera sus cuentas.*
*Ellos fijaron las cuentas en el cuello de la muchacha de forma que no pudieran quitarse.*
*Ellos la tiraron abajo.*
*Sus hombros eran demasiado anchos para permitir su paso y es un imperativo que las cuentas deben cortarse ese día.*
*¿Qué podemos hacer, ellos dijeron?*
*Òwónrín dijo:-¡Olvídense!-*
*-¿Podría romperse la jícara de carga?-*
*-¿Podrían las jícaras de carga rasgarse, y salirse fácilmente?-*
*La jícara usada para pedir prestado el maíz es la que debe usarse para reembolsarlo.*
*Si una gallina desparrama la medicina de uno.*
*Uno romperá sus huevos.*
*Si alguien nos ataca, uno se vengará.*
*Recuerden que tuve que cortar el árbol de cereza en último momento.*
*Así, que también permítanos el corte que uno desea hacer para quitar las cuentas.*
*Así fue cómo la niña fue decapitada.*
*Y la cuenta fue alejada de la cabeza decapitada para Òwónrín.*
*Ogbè lloró amargamente.*
*¿Así el primer ataque, no es tan doloroso como el último?*
*Este verso de Ifá nos enseña a tener auto-control y saber dominarnos internamente en momentos duros, así como saber usar el sentido común en los juicios de la vida.*

***Ogbè imploró a sus babaláwos, pero era ya muy tarde y dijo:***
***Él me despreció.***
***Yo me vengué.***
***Una gallina desparramó mi medicina.***
***Yo rompí sus huevos.***
***La jícara de carga no se romperá.***
***Las jícaras de carga no se rasgan, ni se salen fácilmente.***
***La jícara usada para pedir prestado el maíz es la que debe usarse para reembolsarlo.***
***Permítenos la indulgencia del buen carácter.***
***Òwónrín, ató cuentas en el cuello de la hija de Ogbè y esto resultó que fuese muerta.***

## *Òwónrín Òyèkú*

***Ifá le pide que ofrezca dos platos con ekuru blanco y dos platos más mezclados con aceite usados para proveer a sus enemigos. Ifá le pide que sea cauteloso, que así podrá hacer grandes cosas. Deberá sacrificar para sobrepasar a sus enemigos.***

*Ìrókò jiwà jiwà èyìnkùlé Onígbò*
*Níí şefá fún Onígbò Asùnlólá*
*Ọmọ ajayé Ifá gbindingbindin bi ẹni ń láyin*
*Níjó ti ń sunkún òun ò lájé*
*Wón ní kó rúbọ*
*Wón níre ajé fún un pitipiti*
*Onígbò bá rúbọ*
*Ajé dé fún Onígbò*
*Àşé wọn ò ti jé kí ire è ó wọlé ni*
*Ayé bé yẹ Onígbò*
*Ijó ní ń jó n ní ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Olódùmarè keji ti ń tún ilé ayée şe*
*Àşé ayé le yẹni to báyìí ?*

*Ìrókò jiwà jiwà èyìnkùlé Onígbò*
*Níí şefá fún Onígbò Asùnlólá*
*Ọmọ ajayé Ifá gbindingbindin bi ẹni ń láyin*
*Èyin ẹ wo Ìrókò jiwà jiwà èyìnkùlé Onígbò*
*Gbogbo ara ló fi so bí okùn*
*Gbogbo ara ló fi şe idẹ*
*Gbogbo ara ló fi soa jé winnkinkin kanlè*
*Ayé Onígbò wáá dára.*

***El floreciente árbol del Ìrókò en el patio de Onígbò.***
***Realizó la adivinación a Onígbò Asùnlólá, el hijo de ajayé Ifá gbindingbindin bi ẹni ń láyin, cuando se quejaba de no tener riquezas.***
***Ellos le pidieron que ofrendara y desearon para él mucha riqueza.***
***Onígbò ofrendó y la riqueza llegó a manos llenas para él, y tuvo mucha paz y alegría extendida.***
***Él bailó y alabó a sus babaláwos. Ellos alabaron a Ifá. La Vida le fue placentera.***
***El segundo de Olódùmarè que está envuelto reformando el Mundo.***
***¿Así que usted puede hacer esto agradándome a mí la vida?***
***El floreciente árbol del Ìrókò en el patio de Onígbò.***
***Realizó la adivinación a Onígbò Asùnlólá, el hijo de ajayé Ifá gbindingbindin bi ẹni ń láyin, quien está disfrutando la benevolente vida que Ifá le ha dado como si goteara miel.***
***Miren el floreciente árbol del Ìrókò en el patio de Onígbò.***
***Las cuentas germinando totalmente en el cuerpo.***
***El latón germinando totalmente en el cuerpo.***
***Germinando totalmente desde el dedo del pie hasta la cabeza.***
***La vida de Onígbò será muy buena.***

*Ilú oró wọn ò júgbèé*
*Ilú àjòji wọn ò júhe*
*Íyà ló jẹ àjòji títíítí*

*Ló tara ilú è jejeeje*
*A dífá fún Igi Tééré*
*Èyí ti ń sawoó relé Onígbò*
*Igi Tééré délé Onígbò*
*Ó bá bèrè síí so ajé*
*Onígbò ń kó o*
*Igi Tééré délé Onígbò*
*Ó so èjigbàrà bàbá mokún*
*Onígbò ń kó o*
*Igi Tééré délé Onígbò*
*Ó so lááràngúnkà aṣọ ọba tó koná yanranyanran*
*Onígbò ń kó o*
*Onú è ń dún*
*Àjòji ni ń dá bírà fóun báyìí?*
*Ayé yẹ Onígbò*
*Igbà ó pé sàà*
*Igi Tééré bá so Orí*
*Àwọn èèyàn bá lòó pé Onígbò*
*O ò wáá wo igii rẹ!*
*Igi Tééré ló yọ Orí báyìí?*
*Onígbò ni àfi báa ba gé Igi Tééré*
*Àwọn èèyàn ni ẹ è ráyé bí o?*
*Níwọ Onígbò*
*Igi Tééré so Ajé*
*O ń kó o*
*Ó so èjigbàrà bàbá mokún*
*O ń kó o*
*Ó so lááràngúnkà aṣọ ọba tó koná yanranyanran*
*O ń kó o*
*Igi Tééré wá so orí*
*Ó wáá ni kàwọn ó sá ge igi*
*Wón níwọ Onígbò ṣe pèlépèlé o*
*Ilú oró wọn ò júgbèé*

*Ilú àjòji wọn ò júhe*
*Íyà ló jẹ àjòji títíítí*
*Ló tara ilú è jejeeje*
*A dífá fún Igi Tééré*
*Èyí ti ń sawoó relé Onígbò*
*Igi Tééré ń so Ajé*
*Onígbò ń kó o*
*Ó so èjigbàrà bàbá mokún*
*Onígbò ń kó o*
*Igi Tééré so lááràngúnkà aṣọ ọba tó koná yanranyanran*
*Onígbò ń kó o*
*Ẹ̀ wèèyàn kéèyàn*
*Igi Tééré wáá so orí*
*Onígbò ni á gégi*
*Ệ momo gégi ò*
*Igi Tééré to sorí*
*Onígbò mó ge!*

***Un pueblo lleno de ataques no es fácil vivir allí.***
***Un nuevo pueblo no es fácil para adaptarse a vivir.***
***La severa aflicción sufrida por una persona extranjera.***
***Le hace desear desandar sus pasos atrás y volver a su casa.***
***Lanzó adivinación para el delgado árbol, cuando estaba desarrollando el sacerdocio en la casa de Onígbò.***
***El delgado árbol llegó a la casa de Onígbò y comenzó a producir riquezas, las cuales Onígbò recogía y guardaba.***
***El delgado árbol llegó a la casa de Onígbò y ella germinó lááràngúnkà, el vestido brillante de los reyes, lo cual Onígbò recogió y fue muy feliz.***
***"Un extranjero realiza muchas maravillas para mí"***
***La vida para Onígbò se tornó exitosa y placentera.***
***El delgado árbol germinó una cabeza y las gentes llamaron a Onígbò para que viese ese fenómeno.***
***Y él dijo que había que cortar ese árbol, a causa de esa rara cabeza***

***Ellos dijeron a fritos:***
***-¡Vengan y vean las maravillas de la Vida!-***
***- Cuando el árbol germinó cuentas, las recogisteis, al igual que èjigbàrà, el padre de las cuentas, al igual que lááràngúnkà, el vestido brillante de los reyes, también lo recogisteis –***
***- ¿Pero al germinar una cabeza, nos pides que cortemos el árbol? -***
***- ¡Ejerce el refrenamiento Onígbò! - Las personas avisaron.***
***Un pueblo lleno de ataques no es fácil vivir allí.***
***Un nuevo pueblo no es fácil para adaptarse a vivir.***
***La severa aflicción sufrida por una persona extranjera.***
***Le hace desear desandar sus pasos atrás y volver a su casa.***
***Lanzó adivinación para el delgado árbol, cuando estaba desarrollando el sacerdocio en la casa de Onígbò.***
***Onígbò recogió todos los beneficios que produjo el delgado árbol, pero quiere derribarlo al germinar una cabeza.***
***- ¡Por favor, Onígbò, no llegues a cortarlo! –***

# *Òwónrín Ìwòrì*

***Ifá dice que esta persona ha laborado fuertemente sin ver éxitos, su riqueza depende de su nivel de paciencia. Su riqueza llegará en forma de artículo que todos ignorarán. El sacrificio a realizar será para que las buenas bendiciones no le eviten más.***

*Ìşé ni ò şé Gúnnugún kó bà lóorun*
*A dífá fún Òwónrín ọmọ Aşégilówó*
*Òsi ni ò tÀkàlà kó bà lérùwà*
*A dífá fún Ìwòrì ọmọ Atàpólà sọlà*
*Ìwọ ò sàì là èmi ò sàì là*
*A dífá fún Aláfohùnfojúrí ọmọ Asóru tà ra igba ẹrú*
*Àwọn le là láyé àwọn bí?*
*Wón ní kí wón ó rúbọ*
*Wón ní bí ón bá ti rúbọ*
*Wón ní ìşé tán*
*Ìşé ni ò şé Gúnnugún kó bà lóorun*

Òsi ni ò tÀkàlà kó bà lérùwà
Àwọn ìwọ ò sàì là èmi ò sàì là
Wón ni ìwọ náà ó rà ràà rà
O ó ra igba ẹrú
Wón bá rúbọ
Ni ón bá ń ra igba ẹrú
Wón rú ẹyẹlé
Owó lópòlopò
Ayé bá yẹ wón
Ni wón wá ń jó
Ni wón ń yò
Ni wón ń yin àwọn Babaláwo
Àwọn Babaláwo ń yin Ifá
Wón ni béè làwọn Babaláwo tàwọn wí
Ìşé ni ò şé Gúnnugún kó bà lóorun
A dífá fún Òwónrín ọmọ Aşégilówó
Wón ni kó rúbọ
Yóó là láyé
Òsi ni ò tÀkàlà kó bà lérùwà
A dífá fún Ìwòrì ọmọ Atàpólà sọlà
Wón ní kí Ìwòrì ó rúbọ
Yóó là láyé
Ìwọ ò sàì là èmi ò sàì là
A dífá fún Aláfohùnfojúrí ọmọ Asóru tà ra igba ẹrú
Ẹ̀bọ n wón ni kí wón ó şe
Wón si rúbọ
Wón là láyé o
Ìwọ ò sàì là
Èmi ò sàì là
Gbogbo wa lá ó jọ là ńlé ayé porongodo
Ìwọ ò sàì là
Èmi ò sàì là.

***Ìşé ni ò şé Gúnnugún kó bà lóorun***
***Lanzó Ifá para Òwónrín el hijo de Aşégilówó***
***Òsi ni ò tÀkàlà kó bà lérùwà***
***Lanzó Ifá para Ìwòrì el hijo de Atàpólà sọ̀là***
***Ìwọ̀ ò sàì là èmi ò sàì là***
***Lanzó Ifá para Aláfohùnfojúrí el hijo de Asóru tà ra igba ẹrú***
***Ellos preguntaron a Ifá si serían ricos en toda su extensión.***
***Le dijeron que sacrificaran, que terminado el sacrificio, la pobreza se alejaría de ellos para siempre.***
***Los sacerdotes Ìşé ni ò şé Gúnnugún kó bà lóorun, Òsi ni ò tÀkàlà kó bà lérùwà, e Ìwọ̀ ò sàì là èmi ò sàì là les dijeron que compraran doscientos esclavos, además de palomas y bastante dinero que sería la ofrenda.***
***La vida les cambió para grandes éxitos y beneficios.***
***Ellos alabaron a sus babaláwos, los sacerdotes alabaron a Ifá.***
***Ellos sacrificaron y se convirtieron en personas acaudaladas.***
***¡Tú serás rico, al igual que yo!***
***Todos nosotros seremos afortunados en la vida.***
***¡Tú serás rico, al igual que yo!***

*Òwónrín werere werere*
*Ìwòrì werere werere*
*A dífá fún Okó*
*A bú fún Ẹ̀pọn*
*Níjó ti ón ń tòrun bò wálé ayé*
*Wón ń bí wón pé taa ní ó lọmọ̀?*
*Wón ni kí Okó ó rúbọ̀*
*Kí Ẹ̀pọn náà ó si rúbọ̀*
*Wón şe é*
*Òwónrín werere werere*
*Ìwòrì werere werere*
*A dífá fún Okó*
*A bú fún Ẹ̀pọn*
*Àwọn méjèèjì ń tòrun bò wálé ayé*
*Ẹ̀bọ̀ ọmọ̀ n wón ni kí wón ó şe*
*Wón gbébọ̀ ńbè wọn rúbọ̀*

*Ẹ̀ si gbómọ yín pòn séyin*
*Ẹ̀ gbómọ pòn ẹ kóólé*
*Okó ló wáá lọmọ*
*Ẹ̀pọn ló si lọmọ.*

***Òwónrín werere werere***
***Ìwòrì werere werere***
***Lanzaron Ifá para el Pene y para el Escroto, cuando venían juntos del Cielo a la Tierra.***
***Ellos se preguntaban que quien sería el dueño de los hijos.***
***Se les pidió a ambos que sacrificasen y así ellos hicieron.***
***Òwónrín werere werere***
***Ìwòrì werere werere***
***Lanzaron Ifá para el Pene y para el Escroto, cuando venían juntos del Cielo a la Tierra.***
***Es el sacrificio para tener hijos, lo que se les indicó a ambos.***
***Y ellos cumplieron con la ofrenda.***
***Has decidido cargar tus hijos a la espalda.***
***Has decidido cargar tus hijos a la espalda, y penetrar bien adentro.***
***Es el Pene y el Escroto quienes tienen los hijos.***

# *Òwónrín Òdí*

***La esposa será capaz de darle muchos hijos. La persona será reverenciada por muchos. La persona llora mucho internamente y deberá llamar de manera constante e implacable a Ifá, así como ofrendar para buenas bendiciones.***

*Pòpá kan téérété*
*A dífá fún Àlúkúlàkà*
*Níjó ti ń fomi ojúú sògbéré ọmọ*
*Wón ni ó rúbọ*
*Wón ni wíndin wìndin lọmọ è ó pò*
*Bí àbímọ yè bí àbímọ yè*

*Àlúkúlàkà bí àbímọ yè o*
*À á ṣéé mọ Àlúkúlàkà làá pe Orò*
*A lóun bí wíndin wìndin wíndin wìndin*
*A tún ké*
*Bí àbímọ yè bí àbímọ yè*
*Àlúkúlàkà bí àbímọ yè o*
*Ó bímọ*
*Ọmọ pó kárí ayé.*

***Un palo delgado.***
***Lanzó adivinación para Àlúkúlàkà, cuando se quejaba de no tener descendencia.***
***Se le dijo de sacrificar para tener muchos hijos.***
***Así como exitosos nacimientos.***
***Àlúkúlàkà, como el parto exitoso.***
***Àlúkúlàkà es el epíteto de Orò.***
***Él entona: -¡Yo parí a muchos niños! lo entona agudamente de nuevo, como un parto exitoso.***
***Àlúkúlàkà, tuvo muchos hijos extendidos por el ancho mundo.***

*Kiliwí Awo ilé Alájá*
*Òfàfà lájá ajá Òwónrínsindin*
*Oriri mòjò o mò ṣehuùn mi*
*A dífá fún Oriri mòjò*
*Èyí ti ń sunkún òun ò lájé*
*Oriri mòjò ni ń bèèrè*
*Òun leè lájé báyìí?*
*Wón ní kó rúbọ*
*Wón ní ọkàan rè ó balè*
*Yóó nisinmi*
*Oriri mòjò bá rúbọ*
*Ó bá bèrè síí lájé*
*Ayé yẹ é*
*Ní bá ń yin Kiliwí*
*Awoo wọn ńlé Alájá*

*Àwọn Òfàfà lájá ajá Òwónrínsindin*
*Ni wá ń jó n ní ń yò*
*Ni ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Kiliwí Awo ilé Alájá*
*Òfàfà lájá ajá Òwónrínsindin*
*Oriri mòjò o mò şehuùn mi*
*A dífá fún Oriri mòjò*
*Èyí ti ń sunkún òun ò lájé*
*Wón ní ó rúbọ*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Ifá gbà mí dákun*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Ajé rí mo wí*
*Òpè kóo mó şe gbàgbé*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Aya tí mo wí*
*Òpè kóo mó şe gbàgbé*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Ọmọ tí mo wí*
*Òpè kóo mó şe gbàgbé*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Ilé tí mo wí*
*Òpè kóo mó şe gbàgbé*
*Oriri mòjò gbà mí ò*
*Oriri mòjò gbà mí ò*

***Kiliwí el sacerdote del clan de Alájá***
***Òfàfà lájá el perro de Òwónrínsindin***
***Oriri mòjò, te agradezco tu gesto hacía mí.***

*Lanzaron adivinación para Oriri mòjò, cuando se quejaba a causa de la pérdida de sus riquezas.*
*¿Podré obtener más riquezas? Él se preguntaba.*
*Ellos le pidieron que sacrificara, para que recuperara sus riquezas y también paz mental y sosiego.*
*Oriri mòjò sacrificó y comenzó a obtener lo deseado y expresado.*
*Él estuvo invocando al sacerdote Kiliwí, el adivino del clan de Alájá*
*y a Òfàfà lájá, el perro de Òwónrínsindin*
*Él se regocijó y alabó a sus babaláwos, ellos alabaron a Ifá.*
*Kiliwí el sacerdote del clan de Alájá*
*Òfàfà lájá el perro de Òwónrínsindin*
*Oriri mòjò, te agradezco tu gesto hacía mí.*
*Lanzaron adivinación para Oriri mòjò, cuando se quejaba a causa de la pérdida de sus riquezas.*
*Ellos le pidieron que sacrificara. Y así él lo hizo.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*Ifá, por favor ayúdame.*
*La riqueza que te dije*
*Òpè no la olvides.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*La buena fortuna de esposas de las que te hablé.*
*Òpè no la olvides.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*La buena bendición de hijos de la que te hablé.*
*Òpè no la olvides.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*La buena bendición de la propiedad, casa de la que te hablé.*
*Òpè no la olvides.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*
*Oriri mòjò, por favor ayúdame.*

# ***Òwónrín Ìrosùn***

***Ifá le exhorta a no ser malicioso, para que una buena cantidad de buenas bendiciones, no se alejen. Se deberá sacrificar para no morir prematuramente.***

*Saláámó, Awo ègbé Igi*
*A dífá fún Àkókó*
*Èyí tíí sọmọ wọn ní Ìramòrí*
*Èyí tí ń lọ rèé lókọ nÌrẹsà ọ pè oko*
*Wón ni kó rúbọ*
*Gbogbo àwọn ti ón féràn Àkókó*
*Wón bá bèrè síí sunkún*
*Wón ń pé ó mó lọ*
*Àkókó náà ba bèrè síí sunkún*
*Ó ní bí ón şe şe òun náà ni*
*N ní ó jèé ki òún ó lọ*
*Ijó ní ń jó ayò ní ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Saláámó, Awo ègbé Igi*
*A dífá fún Àkókó*
*Èyí tíí sọmọ wọn ní Ìramòrí*
*Èyí tí ń lọ rèé lókọ nÌrẹsà ọ pè oko*
*Àkókó*
*Mó lọ*
*Ó lóun ó lọ*
*Gbogbo yin lẹ ó gbèé sówó*
*Gbogbo yin lẹ ó pòn séyin*
*Ẹbọ kan ò lè dà bí ẹbọ Àkókó mó o.*

***Las hormigas rojas, el sacerdote del tronco del árbol***

***Adivinó Ifá para Àkókó, su hija en la ciudad de Ìramòrí,***
***cuando se iba a casar en la ciudad de Ìrẹsà ợ pè oko.***
***A ella se le pidió sacrificar.***
***Todos los que amaban a Àkókó, empezaron a llorar.***
***Ellos desearon que ella no partiera y los abandonara.***
***Àkókó también lloraba, debido a la manera buena que ellos la habían tratado.***
***Eso hacía difícil su salida para encontrar a un aspirante en otra ciudad.***
***Ella estuvo bailando y alabó a sus babaláwos y ellos alabaron a Ifá.***
***Las hormigas rojas, el sacerdote del tronco del árbol***
***Adivinó Ifá para Àkókó, su hija en la ciudad de Ìramòrí,***
***cuando se iba a casar en la ciudad de Ìrẹsà ợ pè oko.***
***Àkókó, no te vayas.***
***Ella dijo que tenía que hacerlo.***
***Usted abrazará a todos sus niños con sus manos.***
***Usted a todos los podrá atar a su espalda.***
***Ningún otro sacrificio podría demostrar ser tan eficaz como el sacrificio de Àkókó.***

*Àgbàdo ló yòrùkè*
*Béè ní ò gbó Ifá*
*A dífá fún ợn nìrosùn o pé oko*
*Wón ni wón ó rúbợ*
*Wón rúbợ fún àikú*
*Wón pabợ*
*Wón rúbợ, ẹbợ pé*
*Wón rú girìpá òrúkợ*
*Àikú ba dé fún wợn*
*Èmíin wón gùn*
*Ijó ni wón ń jó*
*Ayò ni wón ń yò*
*Babaláwo ní wón ń yin*
*Àwợn Babaláwo ń yin Ifá*
*Wón ni béè làwợn Babaláwo tàwợn wí*

*Àgbàdo ló yòrùkè*
*Béè ní ò gbó Ifá*
*A dífá fún ọn nìrosùn o pé oko*
*Ệbơ n wón ní wón ó şe*
*Wón si gbébơ ńbè*
*Wón rúbơ*
*Ệbọơ wón dà*
*A rÓnítidi ráikú*
*A wá rÓnítidi kangẹrẹ.*

***Es el maíz que tiene su estigma que ondula como una cola de caballo***
***Aún sin saber ni conocer una palabra de Ifá***
***Lanzó Ifá para ellos en Ìrosùn o pé oko, y les pidió que sacrificaran.***
***Ellos ofrendaron para obtener longevidad, entregaron todos los artículos necesarios para el sacrificio.***
***Y para no sentir la muerte prematura, ofrendaron un desarrollado macho cabrío.***
***Ahora ellos gozan de una muy buena larga vida.***
***Ellos se regocijaron y alabaron a sus babaláwos y estos alabaron a Ifá.***
***Es el maíz que tiene su estigma que ondula como una cola de caballo***
***Aún sin saber ni conocer una palabra de Ifá***
***Lanzó Ifá para ellos en Ìrosùn o pé oko, y les pidió que sacrificaran.***
***Ellos ofrendaron para obtener longevidad.***
***El sacrificio de ellos fue muy eficiente.***
***Nosotros vemos a Onítidi y vemos a la Vida.***
***Nosotros vemos a Onítidi, que está muy viejo y frágil.***

****Este Ifá es también llamado Òwónrín Onítidi****

# Òwónrín Òbàrà

***Ifá dice que existe algo que perteneció a su padre, que se ha mantenido como riqueza por largo tiempo en algún lugar y que no se puede perder. Ifá dice que la persona experimenta una carencia de hijos. Deberá investigar acerca de sacrificar para obtener hijos e ir a la ciudad vecina para realizar este sacrificio. Habrá cantidad de buenas bendiciones para esta persona que su creador le brindará.***

*Òwónrín lawo Gbáro*
*Ọ̀lòbàrà lawo Alè odò*
*A dífá fún Mọnírèré ò sèsè*
*Tí sọmọ Ọlórò kan àtijó*
*Wón ní ó rúbọ*
*Wón ní ọròọ babaa wọn kan àtijó*
*Wón ní ń bẹ ńlè omi*
*Wón ní kó rúbọ kó báà jáde sí i*
*Ó bá rúbọ*
*Tòọ baba è bá jáde sí i*
*Ní wá ń jó n ní ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Òwónrín lawo Gbáro*
*Òbàrà lawo Alè odò*
*A dífá fún Mọnírèré ò sèsè*
*Tí sọmọ Ọlórò kan àtijó*
*A wáá rí ọ réwà a ríre*
*Mọnírèré ò sèsè*
*A wá rí ọ réwà a ríre*
*A wáá rí ọ réwà ó ku ọmọ*
*Mọnírèré ò sèsè*
*A wáá rí ọ réwà ó ku ọmọ.*

***Òwónrín el sacerdote de Gbáro***

***Ọ̀lòbàrà el sacerdote de Alè odò***
***Lanzaron Ifá para Mọnírèré ò sèsè, la hija de un acaudalado hombre ya entrado en años.***
***Le dijeron que ofrendase, ya que la riqueza de su padre, estaba en la margen del río, y debía venir a ella.***
***Ella ofrendó y las riquezas a ella vinieron.***
***Ella bailó y alabó a sus babaláwos, ellos alabaron a Ifá.***
***Òwónrín el sacerdote de Gbáro***
***Ọ̀lòbàrà el sacerdote de Alè odò***
***Lanzaron Ifá para Mọnírèré ò sèsè, la hija de un acaudalado hombre ya entrado en años.***
***Nosotros vemos tu belleza, vemos las cosas buenas de la vida.***
***Mọnírèré ò sèsè***
***Nosotros vemos que tú belleza, sigue estando en los hijos.***
***Mọnírèré ò sèsè***
***Nosotros vemos que tú belleza, sigue estando en los hijos.***

*Ẹ̀dun níí sọmọ Oníyán*
*Òwè níí sọmọ Ọ̀lóbè*
*Èṣù Òdàrà níí sOlúwo Àgbésinkun lóko*
*A dífá fún Ìrè ò sèjè tíí sOlógun Ẹ̀rànhan*
*Wón ní ó rúbọ*
*Ogún si mú nílé*
*Ìrè ní ń bèèrè pé Ogún ò mú òun báyìí?*
*Wón ní kí Ìrè ó rúbọ*
*Ó bá kọrí sí oko*
*Ẹ̀ ó ri ti Ìrè bá kólé lóko*
*Yóò kólé tán yóó tùún yọ òdèdè*
*Ilé ni Ìrè ò sèjè ti kúò*
*Ayé yẹ Ìrè*
*N ní wá ń jó n ní ń yò*
*Ní ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ní béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Ẹ̀dun níí sọmọ Oníyán*

*Òwè níí sọmọ Ọ́lóbè*
*Èşù Òdàrà níí sOlúwo Àgbésinkun lóko*
*A dífá fún Ìrè ò sèjè tíí sOlógun Ḛ̂rànhan*
*Ogún jalé kò dóko*
*Ìrè ò sèjè*
*Ogún jalé kò dóko*
*Ǹgbà ti gbogboo wón gbó pé Ìrè ti kólé sóko*
*Wón bá ń lòó wò ó*
*Ó ni Ogún jalé kò dóko o ò o*
*Ìrè ò sèjè Ogún jalé kò dóko ò ò o*
*Ìrè ò sèjè Ogún jalé kò dóko*
*Ni Ìrè ń wí tée dòni.*

***Los monos son los hijos de aquel que machaca el Ñame.***
***Òwè es el hijo de aquel que cocina el estofado.***
***Èşù Òdàrà, el sacerdote de Àgbésinkun en el campo.***
***Lanzaron Ifá para el Grillo, el soldado silbador y bullicioso, a quien le pidieron que ofrendara para que la guerra que existía en la ciudad no le envolviese a él dentro del conflicto.***
***Él sacrificó y se dirigió al campo.***
***Nosotros siempre veremos al Grillo que levanta su casa en el campo y siempre le hace un balcón o mirador.***
***El Grillo, dejó la ciudad por el campo y la vida le fue placentera.***
***Él cantó, bailó y alabó a sus babaláwos. Ellos alabaron a Ifá.***
***Los monos son los hijos de aquel que machaca el Ñame.***
***Òwè es el hijo de aquel que cocina el estofado.***
***Èşù Òdàrà, el sacerdote de Àgbésinkun en el campo.***
***Lanzaron Ifá para el Grillo, el soldado silbador y bullicioso.***
***La guerra de la ciudad, no llegará al campo.***
***Ìrè ò sèjè.***
***Cuando se escucha acerca de la casa del Grillo en el campo, se le estará rindiendo homenaje.***
***Él chilló “La guerra en la ciudad no llegó a la granja.”***
***Ìrè ò sèjè, la guerra de la ciudad, no llegará al campo.***

***Ìrè ò sèjè, la guerra de la ciudad, no llegará al campo.***
***Es lo que hasta nuestros días, canta el Grillo cuando se le escucha.***

# Òwónrín Òkànràn

***Se ofrecerá sacrificio para evitar muertes y conflictos severos dentro de los hijos. Se respetarán los tabúes y se observará rigurosamente acerca de los artículos de diferentes sacrificios a realizar, incluyendo aquellos que evitarán que propiedades legítimas le sean arrebatadas.***

*Òwónrín pòkàn pòkàn*
*Babaláwo Ẹ̀ja ló dífá fún Ẹ̀ja nínú omi*
*A dífá fún Ìkòrò*
*Èyí tíí sọmọọ wọn lálè odò*
*Ẹ̀bọ ń wón ni ó şe*
*Wón ní kí Ẹ̀ja ó rúbọ*
*Ìkòrò alè odò*
*Wón ní kí òun náà ó rúbọ*
*Alákàn tíí sọmọ wọn ni kòkò odò*
*Wón ní kí òun náà ó rúbọ*
*Şùgbón nígbà tí wón sọ fún Ẹ̀ja àti Ìkòrò*
*Wón ò gbó bí wón ó ti rúbọ*
*Alákàn ńtiè*
*Ó dúó gbó gbogbo ẹbọ è*
*Wón ní òpòlòpò epo lẹbọ*
*Ìgìrìpá òrúkọ lẹbọ*
*Ńtorí ijà àwọn ọmọ aráyé*
*Alákàn lórí òun ò gbó*
*Alákàn bá rúbọ*
*Àwọn Ẹ̀ja ò gbó*
*Ayò ni wón ń yò nínú omi*

*Ńgbà ayò yìí pò lápòjù*
*Èşù bá pé àwọn ayé*
*Ó ní ẹ dáké ni?*
*Ệ è rí Ệja ti ó rúbọ*
*Ti ón ń yò fèrè lódo.*

***Òwónrín pòkàn pòkàn***
***El babaláwo de los Peces, lanzó adivinación para los Peces en el agua.***
***También lanzó adivinación para Ìkòrò, su hijo en el cauce del río.***
***A todos se les pidió sacrificar y que observaran bien el sacrificio.***
***El Cangrejo, su hijo en la otra orilla del río, se le dijo también de ofrendar. Y fue el único de ellos que preguntó acerca de la manera de realizar el sacrificio.***
***Se le dijo de brindar  bastante aceite de palma y 1 chivo desarrollado, a causa de sospechosos ataques que vendrían de sus enemigos terrestres.***
***El Cangrejo no quiso pasar por esa experiencia y sacrificó.***
***Los peces e Ìkòrò, rehusaron ofrendar y se divertían de lo lindo.***
***Cuando su diversión fue incontrolable, Èşù llamó a los hombres (enemigos) y les dijo: ¿No han visto Vds. que ellos no sacrificaron y que su carne es apetitosa?…… ¡vayan allá y cácenlos para su alimento!***

*Aáyán ilé níí forí túgbá*
*Ológbò níí firù tú iyèfun yàgbà yagba ní koto*
*Èkúté ilé a bidí jòtó jòtó*
*Aláňgbá àmù ni ò sáké*
*Aláňgbá àmù ni ò họkùn*
*Ó lé téńté láruru aláruru*
*A dífá fún Ệja*
*Èyí tíí sọmọọ wọn ní pápá*
*A dífá fún Ekú*

*Èyí tíí sọmọ̀ọ wọn nínú ibú*
*Wón ní kí Ekú ó rúbọ*
*Kí wón ó mó baà gba odò lówóọ wọn*
*Ekú ní kín ni ń jẹ béè*
*Ogún si mú àwọn Ẹ̀ja ní pápá*
*Àwọn Ẹ̀ja bá tọ àwọn Àjàlúbòró lọ*
*Wón ni nǹkan wón ó tutù*
*Àwọn Àjàlúbòró bá ṣe Ifá fún Ẹ̀ja*
*Wón ní kí Ẹ̀ja ó tójú Apẹ*
*Wón bá fi òòrí sínú è*
*Wón ní kí Ẹ̀ja ó móọ kùn ún*
*Ẹ̀ja bá kùn òòrí sára*
*Wón bá ní kí Ẹ̀ja ó kọrí sínú omi*
*Wón ní kò séni ti ó bá a jà mó*
*Eku náà si ń bẹ lódò*
*Wón ń yan kán nínú omi*
*Ẹ̀ja bá sá láti pápá*
*Ó bá lòó bá Ekú nínú omi*
*Ẹ̀ja bá múra*
*Ó bá lé Ekú lódò*
*Eku ba sá lọ sínúu pápá*
*Ẹ̀ja bá ń jó ní ń yò*
*Ni ń yin àwọn Àjàlúbòró to kó Ẹ̀ja là lódò*
*Àwọn Àjàlúbòró náà ń yin Ifá*
*Ó ni béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Aáyán ilé níí forí túgbá*
*Ológbò níí firù tú iyèfun yàgbà yagba ní koto*
*Èkúté ilé a bidí jòtó jòtó*
*Aláǹgbá àmù ni ò sáké*
*Aláǹgbá àmù ni ò họkùn*
*Ó lé téńté láruru aláruru*
*A dífá fún Ẹ̀ja*
*Èyí tíí sọmọ̀ọ wọn ní pápá*

*A dífá fún Ekú*
*Èyí tíí sọmọọ wọn nínú ibú*
*Wón ní kí Ekú ó rúbọ*
*Ki Ệja ó mó gbọdò lówóọ rẹ*
*Eku gbébọ béè ni ò rúbọ*
*Ệja nikàn ni ń bẹ léyin to rúbọ*
*Àjàlúbòró ò*
*A dúpé*
*N ló mòmò kỆja là lódò*
*Àjàlúbòró a dúpé*

***La cucaracha de la casa usa su cabeza para rasgar los artículos.***
***El gato usa su cola para quitar el polvo sobre la olla.***
***El ratón de la casa tiene nalgas suaves y musculosas.***
***El lagarto viejo es el único que no bravuconea.***
***El lagarto viejo no roza su vientre cuando se sube encima de alguien.***
***Lanzaron adivinación para el Pez, su hijo en el campo abierto.***
***También para la Rata, su hijo en las profundas aguas.***
***Ellos le pidieron a la Rata que sacrificara para que no fuese apartada de las aguas profundas. Y ella dijo que no existía ninguna fuerza enemiga en el abierto campo que representase peligro alguno para el territorio de las aguas profundas.***
***El Pez se aproximó al sacerdote Àjàlúbòró y este le dijo que su vida podría convertirse en muy fresca y placentera.***
***Àjàlúbòró, preparo una porción de Ifá para el Pez.***
***Y le pidió al Pez que preparara una olla de barro y allí vertió una buena cantidad de manteca de cacao y le pidió al Pez que se lo frotase en el cuerpo y que después entrase al agua.***
***Y le aseguró que nadie podría competir con él dentro del agua.***
***Pero la Rata originalmente vivía dentro del agua, y este era su hábitat.***
***El pez que vino del campo abierto, entró al agua y desplazó a la Rata.***
***El pez se adaptó al agua y la Rata escapó al campo abierto.***
***El pez se regocijó y alabó a sus babaláwos, ellos alabaron a Ifá.***

*El alabó a Àjàlúbòró, que salvó y le dio como medio de hábitat el agua al Pez.*
*Àjàlúbòró alabó e invocó a Ifá.*
*La cucaracha de la casa usa su cabeza para rasgar los artículos.*
*El gato usa su cola para quitar el polvo sobre la olla.*
*El ratón de la casa tiene nalgas suaves y musculosas.*
*El lagarto viejo es el único que no bravuconea.*
*El lagarto viejo no roza su vientre cuando se sube encima de alguien.*
*Lanzaron adivinación para el Pez, su hijo en el campo abierto.*
*También para la Rata, su hijo en las profundas aguas.*
*Ellos le pidieron a la Rata que sacrificara para que no fuese apartada de las aguas profundas.*
*Àjàlúbòró, te agradecemos muchísimo.*
*Eres el único que salvó al Pez en el agua.*
*Àjàlúbòró, te agradecemos muchísimo.*

**Nota:** ***Faltan o no están completos los signos de Òwónrín Ògúndá y Òwónrín Òsá.***

# Òwónrín Òsá

***Una gallina con cinco dedos es el sacrificio para adquirir grandeza y respeto. Si no se pudiese conseguir esa especial gallina, Ifá aceptará cinco gallinas y 1 huevo, el cual será enterrado en un lugar de aseo, pero el iyèrosun será esparcido sobre el huevo antes de taparlo con tierra.***

# <u>Òwónrín Ìká</u>

***<u>Sus cosas no deberán estar en desorden. Él debe ofrecer sacrificio para saber sobre el tratamiento para usar hojas frescas para medicina.</u>***
***<u>Ifá prescribe un pez fresco como elemento sacrílego contra sus enemigos reales. Ese pez deberá picarse en seis o nueve partes, y mezclarse con abundante aceite de palma, para no sufrir daños de sus enemigos y que las cosas le marchen mucho mejor.</u>***

*Olóye lòyé ń yé*
*Ohun táa bá ń ṣe níí yé ni*
*Ìsòwò làá mówòó lò*
*Báa bá ṣéwùú lójà*
*Ká e han ẹni ti ń hunṣọ*
*Agbón ilé wọn ò jiyàn atanná pa*
*Òrun ò jiyàn akùkó*
*Òkété tó bá jalè ẹyin*
*Ní ń filé araa rè han Ikú*
*A dífá fún Ògún*
*Ògún lóun ó joyè Ọba Atúnléayéṣe*
*Wón ní à i í jỌba lái ní Àrèmọ*
*Wón ní táa lÀrèmọò iwọ Ògún*
*Ògún ní Ìká ni*
*Ó ní torí òún dájú*
*Ògún náà ni ón fi ń ṣe idájó láyé tée dòní*
*Wón ní à á wáá tí ṣe?*
*Ẹ̀nikan ò níí fi Ìká joyè e!*
*Olóye lòyé ń yé*
*Ohun táa bá ń ṣe níí yé ni*
*Ìsòwò làá mówòó lò*
*Báa bá ṣéwùú lójà*
*Ká e han ẹni ti ń hunṣọ*
*Agbón ilé wọn ò jiyàn atanná pa*

*Òrun ò jiyàn akùkó*
*Òkété tó bá jalè ẹyin*
*Ní ń filé araa rè han Ikú*
*A dífá fún Òòsà*
*Ó lóun ó joyè Ọba Atúnléayéşe*
*wọn níwọ Òòsà*
*Èèyàn è é jỌba lái ni Àrèmọ*
*Wón ní táa Àrèmọ iwọ Òòsà*
*Ó ní Ìyà ni*
*Òún ó mọ́ọ fi ìyà jẹ gbogbo àwọn èèyàn ni*
*À á wáá ti şe fi Ìyà jẹ Ọba?*
*Olóye lòyé ń yé*
*Ohun táa bá ń şe níí yé ni*
*Ìsòwò làá mówòó lò*
*Báa bá şéwùú lójà*
*Ká e han ẹni ti ń hunşọ*
*Agbón ilé wọn ò jiyàn atanná pa*
*Òrun ò jiyàn akùkó*
*Òkété tó bá jalè ẹyin*
*Ní ń filé araa rè han Ikú*
*A dífá fún Òrúnmìlà*
*Bàbá lóun ó joyè Ọba Atúnléayéşe*
*Wón ní à i í jỌba lái ni Àrèmọ*
*Wón ní táa lÀrèmọ rè?*
*Ó ní ewé ni*
*Ó ni bí nǹkan bá féé bàjé*
*Ó ní Ewé ni ẹ mọ́ọ wá lọ*
*Ewé ó mọ́ọ tún un şe ni*
*Tée dòní*
*Bí nǹkan bá ń şe lágbájá*
*Wón ó pèé ẹ lòó jáwée kinní wá*
*Ewé náà ni wón fi ń túnlé ayé şe*
*Ifá lóun lòún ń túnlé ayéé şe*

*Bí nǹkan ó bàá fi bájé*
*Ewé ni ẹ móọ̀ wá lọ̀*
*Wón wá ń yin Ifá*
*Ìwọ̀ Ifá*
*O fá a tán*
*Ayé yẹ wón ńlé ayé*
*Bí wón ó ṣe Ìpara*
*Bí wón ó ṣe àgbo*
*Bí wón ó sòògùn*
*Ewé náà ni gbogboo rè*
*NIfá wá ń jó n ni ń yò*
*Ni ń yin àwọn Babaláwo*
*Àwọn Babaláwo ń yin Ifá*
*Ó ni béè làwọn Babaláwo tòún wí*
*Olóye lòyé ń yé*
*Ohun táa bá ń ṣe níí yé ni*
*Ìsòwò làá mówòó lò*
*Báa bá ṣéwùú lójà*
*Ká e han ẹni ti ń hunṣọ̀*
*Agbón ilé wọn ò jiyàn atanná pa*
*Òrun ò jiyàn akùkó*
*Òkété tó bá jalè ẹyin*
*Ní ń filé araa rè han Ikú*
*A dífá fún Òrúnmìlà*
*Ó lóun ó joyè Ọ̀ba Atúnléayéṣe*
*Wón ní à I Í jỌ̀ba lái ni Àrèmọ̀*
*Ńjé táa lÀrèmọ̀ rè?*
*Ó léwé ni*
*Ẹ̀ móọ̀ wéwé lọ̀; Ẹ̀ móọ̀ wéwé lọ̀*
*Bó bá di kó bàjé*
*Ẹ̀ móọ̀ wéwé lọ̀*
*A ó wéwé lọ̀ Ìtún Ẹ̀rin*
*Ìtún Ẹ̀rin mò nílé Ewé.*

***Es un intelectual quien mejor entiende los problemas.
Lo absoluto solo está claro para el creador.
Es con un comerciante que uno debe discutir el comercio.
Si nosotros compramos algodón en el mercado.
Nosotros debemos mostrárselo al tejedor.
Una avispa de la casa no conversa con quién se enciende y lo extingue.
El cielo no conversa con un tirador de piedras.
La rata grande es quien se roba la fruta de la palma de aceite.
Fueron quienes lanzaron Ifá para Ògún, cuando comentó que él podría ascender al trono del rey de Atúnléayéşe.
Los creadores de reyes dijeron que: -¡Nadie se convierte en rey sin un Àremọ! –
Y preguntaron: -¿Quién es tú Àremọ, Ògún?
- ¡Es la maldad! – ¡Porque yo soy malo! – él dijo.
Y es el mismo Ògún a quien se usa para medir acerca del castigo.
- ¿Qué podríamos hacer? –
Nadie podrá instalar a la “Maldad” como un rey.
Es un intelectual quien mejor entiende los problemas.
Lo absoluto solo está claro para el creador.
Es con un comerciante que uno debe discutir el comercio.
Si nosotros compramos algodón en el mercado.
Nosotros debemos mostrárselo al tejedor.
Una avispa de la casa no conversa con quién se enciende y lo extingue.
El cielo no conversa con un tirador de piedras.
La rata grande es quien se roba la fruta de la palma de aceite y muestra a la muerte en su casa.
